# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**OṢÙ KẸSÀN, ỌDÚN 2021**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

## OṢÙ KẸSÀN 2021 – ASỌ AGBÁRA

7:00 am – 7:05 am Àdúrà ìbẹ̀rẹ̀
7:05 am – 7:20am Orin Ìyìn àti Ijọ́sìn
7:20 am – 7:35 am Ijẹ́rì
7:35 am – 7:45 am Wákàtí Ìṣìpẹ̀ Àdáṣe
7:45 a m – 8:45 am Iṣẹ́ Ìránṣẹ́
8:45 am - 9:00 am Ọrẹ àti Ìparí ìpàdé

**Orin ibẹ̀rẹ̀**

1. Olúwa gúnwà lórì 'tẹ́
   Àkọ́bí àwọn t'ó sùn
   Òn nìkan L'Onígbèjà wa
   Tó ngbé wa lékè ọ̀tá,
   Alelúyà, Alelúyà
   Jésù li Ónjẹ Ìyè.

2. Àwa njúbà, àwa nṣapẹ
   Kábíyèsí Ọba wa,
   Bùsí ìgbàgbọ́ wa lónìí
   K'a lè túbọ̀ mọ̀ Ọ́ si,
   Alelúyà, Alelúyà
   Ìwọ njọba lárìn wa.

3. Bí a kò tilẹ̀ lè rí Ọ
   Bí t'àwon ti ìgbanì,
   Àwa àt'àwọn Ángẹ́lì
   Nyín irú-ọmọ Jéssè,
   Alelúyà, Alelúyà
   Tẹ́wọ́ gba ìjọsìn wa.

4. Ọ̀d'ágùtàn t'a fi rúbọ
   Ti ṣ'ètùtù f'ẹ́ṣẹ̀ wa
   Kò tún sí ẹbọ míràn mọ́

Ẹ̀jẹ̀ Rẹ ti tó fún wa,
Alelúyà, Alelúyà
Ẹ̀jẹ̀ náà ló nwẹ̀ wá mọ́.

5. Ó nfi ónjẹ ìyè bò wá
Mánnà dídùn lát'ọ̀run
K'ọ́run àt'ayé kọrin náà
Orin 'yìn s'Ọ́d'àgútàn,
Alelúyà, Alelúyà
Ó jìnde, Ó sì gòkè.

## ỌRỌ̀ AGBÁRA

1. Gbogbo àṣọtẹ́lẹ̀ òdì fún àyànmọ́ mi, kí n tó kúrò níbí lónìí, yóò padà sọ́dọ̀ ẹni tó ran an, ní orúkọ Jésù.
2. Lónìí, gbogbo ètò ṣàtánì fún ayé mi yóò wó lulẹ̀, yóò sì kú nípa agbára tó wà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
3. Agbára láti mú àwọn àlá àyànmọ́ mi sẹ, mò n bẹ̀ níbí fún ọ lónìí, gbé ayé mi wọ̀ nípa iná, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo agbára òkùnkùn tó gbasẹ́ láti dènà ìfarahàn àwọn ìbùkún mí níbí lónìí, gba àrá Ọlọ́run, ki ó sì kú, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo agbára tí wọ́n yàn láti mú ìlọra bá ìtẹ̀síwájú mi, lónìí, mo pín ayé mi níyà kúrò lọ́dọ̀ rẹ, nítorí náà, kú, ní orúkọ Jésù.
6. Àwọn ìbùkún tuntun, ògo tuntun, aluyọ tuntun, ẹ̀rí tuntun, ayé mi ṣí sílẹ̀, gbé mi wọ̀ báyìí, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo ẹ̀jẹ̀ búburú, tó n sọ̀rọ̀ lòdì sí àyànmọ́ mi, nípa agbára tó wà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, látòní lọ, o kò ní sọ̀rọ̀ mọ́, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ

**Ìjẹ́wọ́: Orin Dáfídì 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn, sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, dìde, k'Osì pàṣẹ ìgbéga sórí ayé mi, ní orúkọ Jésù.
4. Olúwa, nípa ọwọ́ agbára Rẹ, múmi tẹ̀síwájú, ní orúkọ Jésù.
5. Ọlọ́run, dìde, jẹ́ kí ilẹ̀ mí ṣàn fún wàrà àti oyin, ní orúkọ Jésù.
6. Ohúnkóhun tí yóò jẹ́ kí n dé àwọn ibi gíga, Ọlọ́run, dìde, gbìn ìn sínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo agbára òkùnkùn, tó n fí àyànmọ́ mí ṣeré, kú, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÓ ỌRỌ̀ NÁÀ

**Lúkù 10:19:** kíyèsi i, èmi fún nyín lí àṣẹ láti tẹ ejò àti àkeke mọ́lẹ̀, ati lori gbogbo agbára ọ̀tá: kò sì sí ohun kan bí ó ti wu kí ó ṣe, tí yóò pa nyín-lára.

**II Pétérù 2:9:** Olúwa mọ bí a ti íyọ àwọn ẹni ìwà-bí- Ọlọ́run kúrò nínú ìdánwò àti bí a ti ípa àwọn àláíṣótọ́ tí á njẹ níyà mọ́ de ọjọ́ ìdájọ́:

**Ìsáíàh 54:14:** Nínú òdodo li á ó fì ìdí rẹ múlẹ̀: ìwọ ó jìnà sí ìnira; nítorí ìwọ kì yóò bẹ̀rù: àti sí ìfòìyà, nítorí kì yóò súnmọ́ ọ́.

**Jóélì 2:25-26:** Èmi ó sì mú ọdún wọnnì padà fún nyín wá, èyí tí eṣú òn irú kòkòrò jewéjewé, àti irú kòkòrò kejì, àti irú kòkòrò jewéjewé míràn ti fi jẹ, àwọn ogun nlá mi tí mo rán sárin nyín.

**II Tímótéù 1:7:** Nítorípé Ọlọ́run kò fún wa ní ẹ̀mí ìbẹ̀rù; bíkòṣe ti agbára, àti ti ìfẹ́, àti ti ọkàn tí ò ye koro.

**Fílíppì 4:13:** Èmi lè ṣe ohun gbogbo nínú Krístì ẹnití nfi agbára fún mi.
**Lúkù 10:19:** kíyèsi i, èmi fún nyín lí àṣẹ láti tẹ ejò àti àkeke mọ́lẹ̀, ati lori gbogbo agbára ọ̀tá: kò sì sí ohun kan bí ó ti wu kí ó ṣe, tí yóò pa nyín-lára.

**Éfésù 6:10:** Lákòtán, ará mi, ẹ jẹ́ alágbára nínú Olúwa, àti nínú agbára ipá rẹ.

## ÀṢẸ ÀDÚRÀ SÓRÍ AṢỌ

1. Bàbá mi, jẹ́ kí agbára ọ̀run àtí ti Ẹ̀mí Mímọ́ bà lé asọ yìí báyìí, ní orúkọ Jésù.
2. Mo kédè nípa àṣẹ ọ̀run, lábẹ́ àṣẹ Àgbélèbú, wí pé nígbàtí mo bá fi asọ yìí lé ara mi, yóò fọ àwọn ohun olóró jáde kúrò lára mi, ní orúkọ Jésù.
3. Asọ yìí yóò dábóbò gbogbo ẹ̀yà ara mi. Yóò jẹ́ kí ẹ̀yà ìdábòbó ara mi ru sókè. Yóò mú iwẹ̀nùmọ́ wọ ara mi nínú àti lóde. Yóò dábòbò àwọn ọmọ tí n kò tí ì bí. Yóò fàyè sílẹ̀ fún ẹ̀jẹ̀ Jésù láti ṣàn sí gbogbo ẹ̀yà ara mi. Yóò ti gbogbo irúgbìn òkùnkùn jáde kúrò lára mi, ní orúkọ Jésù.
4. Jẹ́ kí iná Ẹ̀mí Mímọ́, ẹ̀jẹ̀ Jésù àti agbára ìwòsàn Ọlọ́run ṣàn sínú asọ yìí, ní orúkọ Jésù.
5. Bàbá, nípa asọ yìí, ṣọ mí di àrà merìrí, ní orúkọ Jésù.
6. Bàbá, jẹ́ kí asọ yìí pe gbogbo àìsàn ìkọ̀kọ̀ nínú ayé mi níjà, ko sì tì í jáde nípa iná àti nípa ipá, ní orúkọ Jésù.
7. Olúwa, dìde nípa agbára àjínde Rẹ, mí sórí asọ yìí, ní orúkọ Jésù.
8. Ìfóróròyàn fún: ìwòsàn pípé, àlàjá, ìgbéga, ìtúsílẹ̀, ìṣẹ́gun, àseyọ́rí, ìmúṣẹ, àwọn ànfàní atòkèwá, ìgbòòrò, ipọ̀si, ìlọ́po, ìṣerere, ìṣọdọ̀tun, bà lé asọ yìí, ní orúkọ Jésù.
9. Bàbá, jẹ́ kí àṣẹ ọ̀run bà lé asọ yìí, ní orúkọ Jésù.
10. Bí n o ṣe lo asọ yìí, jẹ́ kí agbára Ọlọ́run Alàyè dàpọ̀ mọ, jẹ́ kí ó sọ ìgbà èwe mi dọ̀tun bí ti ìdì, ní orúkọ Jésù.
11. Bàbá, jẹ́ kí ẹ̀jẹ̀ àti omi láti ẹ̀gbẹ́ Jésù Krístì Olúwa tí a gún lọ́kọ́ ṣàn sínú asọ yìí, ní orúkọ Jésù.´
12. Nípa ifòróróyàn tó bà sórí odò Jọ́rdánì, tó fọ ẹ̀tẹ̀ dànù, Bàbá, jẹ́ kí ifòròróyàn Rẹ bà lé asọ yìí láti mú àjàgà to wa lòde àti ti inú kúrò, ní orúkọ Jésù.
13. Bàbá mi, jẹ́ kí asọ yìí di ejò Mósè láti gbé gbogbo ejò ẹ̀mi tó n yọ ìlera mi, ayànmọ́ mi, itẹ̀síwáju mi, alàjá mi, ètò ìṣúná mi, iṣẹ́ mi, iṣèrere mi, owó mi àti ìgbe ayé ẹ̀mí mi lẹ́nu, ní orúkọ Jésù.
14. Bàbá, jẹ́ kí asọ yìí di olùpa ijákulẹ̀, apa idádúró run, olùsọ alàjá jí, ohun- ìjà idòjúkọ, aba àwọn ajàgà jẹ́, olùsọ ògo jí, ní orúkọ Jésù.
15. Ìwọ asọ yíí, mo fi agbára Ẹ̀mí Mímọ́ pè ọ́ níjà, mo sì pàṣẹ kí o gbé àṣẹ ìwòsàn àti okun Ọlọ́run rìn yí ayé mi ká, ní orúkọ Jésù.